

# Oba rere, Oba buruku

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Ojo buruku ni fun Manase. Baba re, Oba Hezikaya sese ku. Nisinsinyi, omo odun mejila pere, Manase je oba titun lori awon eniyan olorun ni Juda, ko ti mo nigba yen, sugbon Manase yoo je oba fun odun marundinlogota, Manase nilo iranlowo lati je oba rere.



Sugbon Manase ko Olorun sile o si n se ti esu.  Manase tun pepe orisa ko.  O gbe ere, o si gbe e kale lori pepe mimo Olorun. Olorun ti so lati enu Mose, "Iwo ko gbodo gbe ere.  Iwo ko gbodo fori bale fun won, tabi ki o sin won."



Manase n se ise ajee o si lo afose. Osi mu ki awon eniyan yipada kuro niwaju Oluwa. Oba sun omo re lati fi se irubo si orisa. Manase se aigboran, Oluwa si binu sii gidigidi.



Nigba ti awon eniyan naa se aigboran, Olorun fi aye gbaa lati je won niya.  Eleyi lo sele si Manase ati awon eniyan to n se akoso le lori.  Oluwa mu awon balogun Asiria wa ba won.  A si fi sekese gbe Manase lo si Babeli.





Pelu inira ni Babeli, Manase be Oluwa, olorun re, o re ara re sile gidigidi niwaju Olorun baba re, O gbadura si i, kosi adura fun orisa oku mo! Sugbon, se Olorun alaaye yoo situn gbo adura Manase mo pelu iwa ika re.

Beeni, Olorun gbo adura oba a si mu pada wa si Jerusalemu, sinu ijoba re, lati maa joba lori awon eniyan. Nigba naa ni Manase mo pe OLUWA ni Olorun.



Oba Manase di eni oto. O ko gbogbo ere jade kuro ninu tempili Olorun ti o wa ni Jerusalemu. O da gbogbo won nu, o tun pepe OLUWA ko. O si ru ebo ope. O pase ki awon eniyan maa sin OLUWA Olorun Isireli. Ewo iyipada Manase!



Nigba ti Manase ku, omo re, Amoni, yipada lati maa bo orisa, ko si re ara re sile niwaju Oluwa bi i ti baba re manase.  Amoni dese pupo pupo, awon iranse re pa ni ikeyin, ninu ile re.  O joba fun odun meji.



Oba miiran ni, Josiah, eni odun mejo ni.  O joba fun odun mokanlelogbon o si se eyi ti o to loju Olorun.  O ba gbogbo esin eke ati Olorun eke je, koda, Josaya gun awon orisa naa kunna.



Oba rere Josiah we ile naa mo, o si tun tempili Olorun se.  Ninu ohun ti ko dara yii won ri iwe ofin Olorun ti o fi fun Mose.





Nigba ti oba gbo oro ofin, o fa aso re ya ni ibanuje. Josiah mo wi pe awon baba nla re ti se aigboran buburu si ofin Olorun.

Woli obinrin Huldah je ise Olorun fun Josiah, “Bayi ni Oluwa wi, ‘kiyesii, emi o mu gbogbo egun ninu iwe wa si ihinyi nitori ti a ko mi si le,’” sugbon nitori ti Josiah re ara re sile ti o si gboran, eyi konii ribe e titi di eyin iku re.



Olorun ran Josiah lowo lati je ki awon eniyan pada leyin Olorun. Ni ojo kan, nigba ti on ko awon omo ogun lo si oju ogun, Josiah fi ara pa gidigidi lati owo awon tafatafa. Awon iranse re sigbe lo si ile re pelu keke ogun lo Jerusalemu nibi ti o gbe ku. Gbogbo awon eniyan re si sofo ati pelu orin-ekun nipa oba Josiah rere.





Leyin oreyin, ijoba naa pari, sugbon ni ojo kan, oba kan yoo tun dide ni Isreli. Oruko re ni OBA AWON OBA ATI OLUWA AWON OLUWA. Nigbati Jesu Kristi wa ni akoko, awon eniyan ko o, won si kan an mo agbelebu. Nigbati Jesu Kristi tun pada wa, ko nii je Oba lori Isreli nikan, bikose lori gbogbo aye.

Oba rere, Oba buruku

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Kronika Keji, ori ketalelogbon titi de kerindilogoji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.